# ÀKÓTÁN ÈDÈ DÍDÁN ÌLÀNÀ ÀTÌLẸ́YÌN ÌSÚNÁ ÌTỌ́JÚ ÌLERA

## Àkópọ̀

Gẹ́gẹ́ bí ìpinnu láti mú ìlera àwọn tó wà lágbègbè rẹ sunwọ̀n sí i, ní pàtàkì àwọn tálákà àti aláìní, àti gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ ìránṣẹ́ ètò ìmúláradá Jésù, Bon Secours Mercy Health fi ara jì láti pèsè ìrànwọ́ owó fún àwọn aláìsàn rẹ̀. Èyí ni àkópọ̀ ìlànà ìrànwọ́ ìṣúná ìlera ti Bon Secours Mercy Health (HFA) tó wà fún ilé ìwòsàn títí dórí Bon Secours Mercy Health Emporia LLC, Bon Secours Mercy Health Franklin LLC, àti Bon Secours Mercy Health Petersburg LLC.

## Wíwà fún Àtìlẹ́yìn Ìsúná

Agbára aláìsàn tàbí olùdúró rẹ̀ ló máa pinu ìkúnjúwọ̀n fún àtìlẹ́yìn ìsúná láti sanwó lẹ́yìn tí o ́ bá ti lo gbogbo àwọn ohun èlò tàn tí o sì ti rí àyè sí gbogbo àwọn ètò àtìlẹ́yìn tán. Ìrànwọ́ owó wà fún ìtọ́jú pàjáwìrì àti ìtọ́jú ìlera míì tí àwọn ilé ìwòsàn Bon Secours Mercy Health ti Southeastern Virginia pèsè (àti àwọn olùpèsè míràn) fún àwọn aláìsàn tí kò ní ìdójútòfò àti àwọn tí ìdójútòfò wọn kò tó, tí wọ́n ń gbé ní àgbègbè tí àwọn ilé ìwòsàn Bon Secours Mercy Health ti ń ṣiṣẹ́, tí owó tó ń wọlé fún wọn kò kọjá ìlọ́po mẹ́rin gbèdéke ìpele Àìní tí Ìjọba Àpapọ̀ (FPG) fi lélẹ̀.

## Àwọn Àmúlò Ìkúnjúwọ̀n

A máa ń pinu àtìlẹ́yìn ìsúná nípa sísún òdiwọ̀n àpapọ̀ ìwọlé owó ìdílé lórí FPG. Ẹnikẹ́ni tó kúnjúwọ̀n fún àtìlẹ́yìn ìsúná lábẹ́ Ìlànà wa pẹ̀lú ìpele ìwọlé owó ní 200% FPG tàbí kéré si ma gba ìtọ́jú ọ̀fẹ́. Ẹnikẹ́ni tó ní ìpele ìwọlé owó láti 201% si 300% FPG, àti 301% sí 400%, máa gba ẹdínwó ìtọ́jú lórí òdiwọ̀n sísún, bi a ti sètò nínú Ìlànà. Ìdíwọ̀n ọ́gọ̀rún pàtó fún 201%-300% FPG, àti 301% sí 400% FPG, a máa ń ṣèmúdójúwọ̀n àwọn ìpele ìwọlé owó ní ọdọdún fún ojà kọ̀ọ̀kan pẹ̀lú àwọn ìyípadà nínú olorí ìdíye.

Kòsí ẹni tó kúnjúwọ̀n fún àtìlẹ́yìn ìsúná lábẹ́ ìlànà HFA tí a ma díyelé fún pàjáwìrì tàbi ìtọ́jú ìlera tó nílò ju iye tí a máa ń gbà àwọn tí ó ní ìsúra irú ìtọ́jú náà. Tí ẹnìkan bá ni ètò ìsúra tó tó tàbí dúkìá wà láti sanwó fún ìtọ́jú, ẹni náà le yàn láti máà kúnjúwọ̀n fún àtìlẹ́yìn ìsúná. Fún àwọn aláìsàn tí kò ní ìsúra tí kò kúnjúwọ̀n fún ẹ̀dínwó àtìlẹ́yìn ìsúná tí a ṣàpèjúwe nínú ìlànà HFA, Bon Secours Merch Health nawọ́ ẹ̀dínwó (sanwó-araẹni) sí owó ilé ìwòsàn wọn. Jọ̀wọ́ kànsí Ìlànà HFA ní kíkún fún àlàyé ẹ̀kúnrẹ́rẹ́.

## Nípa Ètò Ìgbaniwọlé

Ètò fún gbígbani fún àtìlẹ́yìn ìsúná lábẹ́ Ìlànà HFA wa ní àwọn ìgbésẹ̀ wọ̀nyí́:

- Parí Fọ́ọ̀mù Ìgbaniwọlé HFA kí o sì fi àwọn àkọsílẹ̀ tí a nílò si.
  - A máa wo ìwọlé owó rẹ àti ìwọ̀n ìdílé rẹ láti pinu ìpele àtìlẹ́yìn tó wà fún ọ. A lo òdiwọ̀n sísún, lóri FPG tí a kọ ṣókè.
  - A bèrè pe ́ o gbọ́dọ̀ kọ́kọ́ wo ìkúnjúwọ̀n fún irú àwọn àǹfàní ìsúra tí máa le se ìtọ́jú rẹ (bíi owó ọ̀ṣìṣẹ́, ìsúra ọkọ̀, àti bẹ́ẹ̀bẹ́ẹ̀lọ.) A le ṣèrànwọ́ láti darí rẹ sí àwọn ohun èlò to péye.
- A má kànsí sí ọ láti ṣọ fún ọ bóyá o kúnjúwọ̀n fún àtìlẹ́yìn lábẹ́ Ìlànà HFA wa.
- A le ṣèrànwọ́ fún ọ láti ṣètò ìsanwó fún àwọn ìdíyelé tókù tàbi àwọn owó tí kò sí lábẹ́ Ìlànà HFA wa.
  - Ètò ìsanwó máa ṣàyẹ̀wò ipo ìsanwó rẹ láti ṣètò àwọn ìsanwó ti o le ṣàkóso.

## Ibi ti a ti le Gba Ìwífún

O lè gba ẹ̀dà ìwé ìlànà HFA àti fọ́ọ̀mù HFA, títí kan ìsọfúnni nípa bí àwọn èèyàn ṣe lè béèrè fún ìrànwọ́ owó fún ìtọ́jú ìlera: (i) nípa kíkàn sí ìkànnì wa ní www.bsmhealth.org/financial-assistance, àti www.fa.bonsecours.com, tàbí , (ii) nípa kíkàn sí Patient Financial Services lórí fóònù wọn 1-804-765-5557, (iii) nípa kíkọ̀wé ìbéèrè ránṣẹ́ sí Bon Secours Southside Regional Medical Center, 200 Medical Park Blvd., Petersburg, VA 23805 Àkíyèsí: Ìmọ̀ràn lórí Ìṣúnná (Financial Counseling), tàbí (iv) nípa kíkàn sí àwọn agbaninímọ̀ràn wa lórí ọ̀rọ̀ ìṣúná, ní tàràtà ní èyíkéyìí lára àwọn ilé ìwòsàn wa (wo ìwé ìlànà HFA wa fún ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ ìsọfúnni nípa àdírẹ́sì àwọn ilé ìwòsàn wa).

A gba gbogbo àwọn ènìyàn pàtàki tí Bon Secours Merch Health n ṣiṣẹ́ fún tí kò ní ìmọ̀ Gẹ̀ẹ́sì nípa títúmọ̀ àwọn ẹ̀dà Ìlànà HFA wa, Fọ́ọ̀mù Ìgbaniwọlé àti Àkótán yí nínú àwọn èdè tí àwọn ènìyàn náà ń ṣọ. A tún le yàn láti lo àwọn ìrànlọ́wọ́ ìtumọ̀, àwọn ìtọ́ni ìtumọ̀, tàbi pèsè àtìlẹ́yìn nípa lílo àwọn ògbufọ̀ elédè méjì tókúnjúwọ̀n.